# Ṣégeṣège Àrùn inú ẹ̀jẹ̣

Ẹ̀dà Nàìjírìa

Ile eko alakobere

Ìlèra àti Àbò

Ile eko girama

Ìtọ́ni sí Àkóso Ilé Ẹ̀kọ́

A gba ìwé àṣẹ iṣẹ́ yìi lábẹ Creative Commons. Yàtọ̀sí àmì ìdámọ̀ ERSC lóju èwé tó kẹ̀hìn, alè lo iṣẹ́ yìi lọ́fẹ̀ kí a sì pin níwọ̀n ìgbà tí a bá gba àṣẹ àti ìbọwọ́lù olóhun. Alè ṣe ẹ̀dà rẹ̀ fún lílò, níwọ̀n ìgbà tí a bá lèṣe alábàpín èsì àbájàde rẹ̀ pẹ̀lú ẹgbẹ́ àrùn inú ẹ̀jẹ̀ nípa Sickle Cell Open: Online Topics and Education Resources (SCOOTER) project ni www.sicklecellanaemia.org.

Ìfifún: CC-BY-SA, Simon Dyson, ìfipámọ́ ẹ̀tọ́ kan
Simon Dyson
Ẹ̀ka fún Ẹ̀kọ́ Àjọṣepọ̀ ti ṣégeṣège Ẹ̀jẹ̀ àti Àrùn inú ẹ̀jẹ̀,
De Montfort University,
Leicester, United Kingdom
sdyson@dmu.ac.uk

A ó dúpẹ́ lọ́wọ àwọn wọ̀nyii fún ṣiṣé ìmúgbòòrò ìtọ́ni sí àkóso ìlànà ẹ̀kọ́ ẹ̀yà ti Nàìjíria:
• Bola Ojo,
• Naomi Maiguwa,
• Jonah Lah
• Dr Baba Inusa
• Comfort Okolo
• Elizabeth Anionwu

A ó dúpẹ́ lọ́wọ́ àwọn wọ̀nyíi fún àgbéyẹ̀wò ribiribi ti akọ̀sílẹ̀ ìlànà ìtọ́ni ti àtìlẹ̀bá ti UK :
• Ọ̀jọ̀gbọ́n Elizabeth Anionwu, CBE, Ọ̀jọ̀gbọ́n Ọmọ̀wé jùlọ ti Nọ́sì, Ifáfitì ti Ìwọ̀ òòrùn Lọ́ńdónù.
• Suzi Crawford, Nọ́sì Akọ́ṣẹ-mọ́ṣẹ́ Agbaninímọ̀ràn, Ibi ìtọjú Ìlera Soho, Birmingham.
• Dr Paul Telfer, Olùkọ́ Àgbà nínu ìmọ̀ nípa Ẹ̀jẹ̀ ní Queen Mary, Ifáfitì ti London, àti Olùkànsí Onímọ̀ nípa Ẹ̀jẹ̀ ní St Bartholomew àti The Royal London NHS Trusts.

**Ìlera àti Ìdábòbò ní Ilé Ẹ̀kọ́**

Ìwé pélébé tí a ṣe yìi dá lórí ìwádìi tí ó ṣàyẹwò ìrirí àwọn ọ̀dọ́ tí ó ní àrùn inú ẹ̀jẹ̀ ní àwọn ilé ẹ̀kọ́. Pàtàkì ẹ̀ka ilé ẹ̀kọ́ ni rírí Pàtàkì ìtọjú àwọn ọ̀dọ́ tí ó ní àìsàn ọ̀jọ pípé, pààpáà jùlọ níwọ̀n ìgbà tí ó jẹ́ pé àkókò ìpẹ́ẹ́rẹ̀ wọn ni wọ́n lò jùlọ ní lílọ ilé ẹ̀kọ́. Ìlànà Ètò Ìlera Nàíjíríà fún Ilé Ẹ̀kọ́ ti Oṣù Bélú 2006 pé fún ohun èlò tí ó pòjùwọ́n àti ètò tí ó ṣàgbélárugẹ ara, ọpọlọ, ààbò àti ìbárá-ẹni-lò ti gbogbo ọmọ ilé ẹ̀kọ́ pátápátá

**Kíni Ségesège Àrùn Inú Ẹ̀jẹ̀ (SCD)?**

Ségesège àrùn inú ẹ̀jẹ̀ (SCD) ni orúkọ àpapọ̀ fún oríṣii ipò àjogúnbá tó léwu tí ó le ṣàkobá gbogbo ẹ̀yà ara. Òhun ni lára àwọn àrùn àjogúnbá tí ó wọ́pọ̀ lágbàye tí ó sì ń kọlu ènìyàn kan láàrín àadọ́ta ènìyàn nínu gbogbo ọmọ tí a bí ní Nàíjírìa. Ségesège àrùn ẹ̀jẹ̀ yíi jẹmọ́ ìpòrurù ìnilara ẹ̀jẹ̀ tí a ń pè ní ìdárùdápọ̀ ìnira inú ẹ̀jẹ̀. Àwọn tí ó ní ségesège àrùn ẹ̀jẹ̀ yíi ní irúfẹ́ ohun tí ń fún ẹ̀jẹ̀ ní àwọ̀ kan (tí a mọ̀sí haemogblobin S (HbS) tàbí àìsàn inú ẹ̀jẹ̀) èyí tí ó yàtọ̀ sí ẹ̀jẹ̀ àgbàlagbà tí ó wọ́pọ̀ (haemogblobin A tàbí HbA). Èyí lè fa kí ẹ̀jẹ̀ pupa láti yíi ìrisí padà kí ó sì dí inú iṣan ẹ̀jẹ̀, tí ó ń fa ìnira ńlá. Ọ̀pọ̀ ẹ̀yà ara ni èyí lè ṣàkobá èyí tí ó túnmọ̀sí pé oríṣii ẹ̀yà ara pàtàkì lé bàjẹ́ ó sì le fa oríṣii àmì ní oríṣii ẹ̀yà ara. Oríṣii àrùn ẹ̀jẹ̀ tí ó wọ́pọ̀ ní ségesège àiléra àrùn ẹ̀jẹ̀, àrùn haemoglobinSC àti àrùn ẹ̀jẹ̀ tí ó ṣàkóbá iṣé àti ìrisí ẹ̀jẹ̀.

[1] *World Health Organization* (*2006*) *Sickle Cell Anaemia*. WHO Fifty-Ninth World Assembly A59/9, Geneva

**Báwo ni a ṣe lè ẹ́kun àmì àrùn ségesège àrùn inú ẹ̀jẹ́ (SCD)?**

Àwọn ohun kan ni a ti ṣe àwarí pé o kópa nínu ìṣokùnfa ìdàrúdápọ̀ àrùn inú ẹ̀jẹ̀. Lára wọn ni àkóràn, òtútù àti/tàbí afẹ́rẹ́ tútù, èérí, gbígbẹ omi ara, ìnìra ìṣákun, ìníra, ìyípadà òjìjì ojú ọjọ́, ọtí líle, kàfénì, àti sìgá mímu. Ìmọ̀ràn fún àwọn tí ó ní àrùn inú ẹ̀jẹ̀ lóri ìdẹ́kun ìdàrúdápọ̀ ni kí wọ́n yẹra fún ìbà, kí wọ́n wà níbi ìlọ́wọ́wọ́, jẹ oúnjẹ tó péye, maa ṣe eré ìdarayá níwọ̀nba, maa mu omi púpọ̀, maa ṣàyẹwò ara nígbà tí wọ́n bání ibà, tó bá dàbí ara wọn ò péye, tí ó bá rẹ̀ wọ́n gidi tàbi wọ́n wà nínu ìrora. Yẹra fún sìgá àti ọtí mímu, maa lòogùn àti abẹ́ẹ́rẹ́ déédéé (pẹ̀lú àwọn òògùn ìdẹ́kun ìbà), kí ó sì dín ìrora kù.

**Àgbekalẹ̀ ọnà ìdẹ́kun láti ṣèrànwọ́ fún àwọn tí ó ní SCD**

Níwọ̀n ìgbà tí àwọn tí ó ní SCD kòle ṣe iṣẹ́ agbára, ó wá ṣe pàtàkì fún wọn láti gba ìdánilẹ́kọ̀ tó yèkoro, ojúlówó egbògi àti ìtọjú ìbáṣepọ̀ àti ìmọ̀ràn iṣẹ́ tó dánmọ́rán.

***Àìwá Ilé ẹ̀kọ́:*** Bí ilé ẹ̀kọ́/kọ́lẹ̀jì kòbání àgbékalẹ̀ ìdúrótini tó lẹ́sẹ̀ nílẹ̀ fún ségesège àrùn **inú** ẹ̀jẹ̀ láti dẹ́kun àìwá sílé ẹ̀kọ́, ìwádìi ti ṣàlàyé pé akẹ́ẹ́kọ̀ tí ó ní SCD lé pa ilé ẹ̀kọ́ jẹ fún ọ̀sẹ̀ mélòo kan nínu ọdún ìkàwé, bí kí ó má wà ní ọjọ́ méjì sí mẹ́ta lẹ́ẹ̀kànna. Ọ̀pọ̀ akẹ́ẹ́kọ̀ tí ó ní SCD ni wọ́n kíi rí ìkinlẹ́hìn láti ọ̀dọ̀ ilé ẹ̀kọ́ láti lèṣe ohun tí wọ́n pàdánù lákòkò tí wọ́n kò wá sílé ẹ̀kọ́. Àwọn akẹ́ẹ́kọ̀ wọ̀nyíi tí wọn kíi wá jù ni wọ́n kíi ṣe daadaa nínu ẹ̀kọ́ wọn. Àwọn díẹ̀ le máa pa ilé ẹ̀kọ́ jẹ lọ́pọ̀lọpọ̀. Ó dára bí wọ́n kòbá rí irúfẹ́ akẹ́ẹ́kọ̀ bẹ̀ẹ̀ gẹ́gẹ́bí ìsáǹsá. Òbí, àwọn akẹ́ẹ́kọ̀ míìràn àti gbogbo àwùjọ gbọ́dọ̀ rí lílọ ilé ẹ̀kọ́ gẹ́gẹ́bi ohun tí ó tọ́ fún ọmọdé tó ní SCD. Ẹ̀kọ́ jẹ́ ìdókòwò ọjọ́ iwajú fún ọmọdé tí ó ní SCD.

**Ìhùwàsí Tó Dára: ÀÌWÁ ILÉ Ẹ̀KỌ́**

Ilé ẹ̀kọ́ kan ní àṣà láti maa kẹ́ẹ́kọ̀ ìrọ̀lẹ́ lóórekòore lẹ́hìn tí wọ́n jáde nílé ẹ̀kọ́. Àwọn olùkọ́ maa ń pín ara wọn láti ṣàbojútó ibi ìkẹ́ẹ́kọ̀ kí àwọn akẹ́ẹ́kọ̀ tí ó pàdánù ẹ̀kọ́ kan fún ìdíkan tàbí òmíìràn lénì ìrànwọ́ láti ṣe ohun tí wọ́n pàdánù níwájú àwọn olùkọ́. Èyí kíi ṣe ìrànwọ́ fún ẹni tí ó ní àrùn inú ẹ̀jẹ̀ láti lèṣe ohun tí ó pàdánù nìkan, ṣùgbọ́n ó tún ń ṣèrànwọ́ kí wọ́n máa bá rí ara wọn gẹ́gẹ́bí ẹnití ó yàtọ̀ sí àwọn akẹ́ẹ́kọ̀ yóokù.

**Ìhùwàsí Tó Dára: ÈTÒ ÌRÀNWỌ́ ẸLẸ́GBẸ́**

Ìṣàkóso tí ó dára míìràn ni àgbékalẹ̀ ètò ìkọ́ni ẹlẹ́gbẹ́ níbi tí akẹ́ẹ̀kọ̀, pàápàa àwọn ọmọdé tí ó ní SCD tí o pa ẹ̀kọ́ kan jẹ, kọ́ láti ọ̀dọ̀ ẹlẹgbẹ́ wọn ní ilé ẹ̀kọ́ lẹ́hìn ìkẹ́ẹ̀kọ̀. Àwọn ilé ẹ̀kọ́ kan ní Nàìjírìa ti bẹ̀rẹ̀ Ìkọ́ni Akẹ́ẹ̀kọ̀, Àwòkọ́ṣe àti Ètò Ìgbàní-níyànjú, níbi tí a ti ń ṣàyẹ̀wò àìléra akẹ́ẹ̀kọ̀ kọ̀ọ̀kan níle ẹ̀kọ́ láti ran akẹ́ẹ̀kọ̀ lọ́wọ́ láti ṣàtúnṣe, lọ àti ṣe dáadáa ní ilé ẹ̀kọ́. Ó ṣèéṣe fún ọmọ tí ó ní SCD láti mọ ohun tí wọ́n pàdánù láti ọ̀dọ̀ àwọn ọ̀rẹ́ ẹlẹgbẹ́ wọn. Rántí pé àwọn ọmọdé tí ó ní SCD maa ń wà nílèra lọ́pọ̀ ìgbà nítorí nàá wọ́nlè ṣèrànwọ́ fún àwọn ẹgbẹ́ wọn tí ó lè pa ilé ẹ̀kọ́ jẹ fún ìdí míìràn yàtọ̀sí àìsàn tí ó jẹmọ́ àrun inú ẹ̀jẹ̀. Èyí jẹ́ ẹ̀kọ́ pàtàkì pé àwọn ọmọdé tí ó ní SCD lè jẹ́ olùfúnni ní ìrànwọ́ àti àtìlẹ́hìn àti wọ́n tún jẹ́ olùgba ìrànwọ́ àti àtìlẹ́hìn.

***Omi:*** Àwọn ọmọdé tí ó ní SCD gbọ́dọ̀ lómi lára dáradára láti dẹ́kun àìsàn.
Kí wọ́n ní ìpèsè fún omi mímọ́. Kí wọ́n gbàwọ́n láyè láti mu omi nínu kíláasì. Ní àwọn ilé ẹ̀kọ́ kan, ìyàrá ìkẹ́ẹ̀kọ̀ kọ̀ọ̀kan ní ike omi, pẹ̀lú ife fún omi mímu asì fàyègba akẹ́ẹ̀kọ̀ kọ̀ọ̀kan láti mu ife omi mímu wa kíláásì. Àṣà jíjẹ àti mímu ní ilé ẹ̀kọ́ gbọ́dọ̀ jẹ́ èyí tí àwọn fàyègba ọmọ tí ó ní SCD láti gbé omi wá ìyàrá ìkẹ́ẹ̀kọ̀ nígbà tí wọ́n bá nílò rẹ̀. Ri dájú pé orísun omi ń ṣiṣẹ́ kí o sì wà ní ìmọ́tótó kí àwọn ọmọdé tí ó ní SCD lè lo wọn kí a sì dẹ́kun àkóràn.

***Lilo ile Igbọnsẹ:*** Awọn ti o ni SCD kole da itọ duro bi awọn ẹlomiran. Wọn maa n ni itọ ti a là lọpọlọpo wọn si ni lati lọ ile igbọnsẹ lọpọ igba. Maṣe dẹkun akoko ijade lọ ile igbọnsẹ.

**Ìhùwàsí Tó Dára: LÍLO ILÉ ÌGBỌ̀NṢẸ̀**

Ilé ẹ̀kọ́ kan ti ṣàgbékalẹ̀ ètò fífún àwọn ọmọ ní káádì tí ó sọ pé àwọn ọmọ ní ẹ̀tọ́ láti gbàyè láti lọ ilé ìgbọnsẹ̀ lákokò ẹ̀kọ́.

***Rírẹ̀:*** Ẹni tí ó ní SCD lè ní ìrirí àìtó ẹ̀jẹ̀. Èyí lè túnmọ̀ sí kó rẹ̀ wọ́n, ṣíṣú ojú àti àìlèfiyèsí. O lè rẹ̀ wọ́n débi pé kí wọ́n nílò ìsinmi. Ó ṣe pàtàkì kí olùkọ́ má rì àmí àrùn àìlera yíi ti SCD gẹ́gẹ́bí ìmẹ́lẹ́.
Gígùn àìníye àjà lọ́pọ̀ ìgbà lóòjọ́ ní lílọ kíláásì jẹ́ ìnira fún àwọn ọmọdé tí ó ní SCD.

***Ègbò Ẹsẹ̀ Àdáìjiná:*** Àwọn ọmọ kan tí ó ní SCD lè máa ní ìrirí ìnira àti ègbò ẹ̀sẹ̀ àdáìjiná lórèkoorè, lọ́pọ̀ ìgbà ní ojúgun, tí kìí tètè jiná. Rírìn lè niran kí ó sì mú ègbò àdáìjiná burú. Ilé ẹ̀kọ́ gbọ́dọ̀ ri dájú pé àyiká wọn yẹ fún èyí tí ó lè gba àwọn ọmọdé tí ó ní egbò ẹ̀sẹ̀ àdáìjiná.

**Ìhùwàsí Tó Dára: ILÉ Ẹ̀KỌ́**

Ilé àti àgbékalẹ̀ ilé ẹ̀kọ́ gbọ́dọ̀ pẹ̀lú ìgbímọ̀pọ̀ àwọn tí ọ̀rọ̀ kán pẹ̀lú àwọn akẹ́ẹ̀kọ̀ tí ó ní SCD àti ẹbí wọn. Àgbékalẹ̀ tí ó yẹ gbọ́dọ̀ fí wọ̀nyíi sí ọkàn:

- Àbáwọlé: Ipò tí ó ṣé ṣíwájú nínu àgbékalẹ̀ ilé ẹ̀kọ́ olókè-gogoro KÒNÍ ṣe ànfààní fún akẹ́ẹ̀kọ̀ kékeré tí ó ní SCD tí ó lè ṣe àìlera láti ara àìpéye ẹ̀jẹ̀ tàbí tí ó ní ìrora láti inú egbò ẹ̀sẹ̀ àdáìjiná.
- Àlàfo: Ààyò àlàfo, yàtọ̀ sí ìyàrá ìkẹ́ẹ̀kọ̀, gbọ́dọ̀ wà kí àwọn ọmọdé tí ó ní SCD lè sinmi nígbà tí wọ́n bá ṣàìsàn, bóyá láti gbàwọ́n láyè láti padà sí kíláásì bóyá. Ìyàrá yíi lè tún jẹ́ ibi tí wọ́n kó àwọn òògùn àti aporó wọn sí tí a síi fún wọn nígbà tí ó bá nídì.
- Ìmọ́tótó àti ìṣàkóso àkóràn: Ohun èlò ilé ẹ̀kọ́ orí inú ilé ní a gbọ́dọ̀ yàn pẹ̀lú àwọn ọmọdé tí ara wọn kòní ààbò lòdí sáárùn púpọ̀, àwọn akẹ́ẹ̀kọ̀ bi àwọn tí ó ní SCD, lọ́kàn, kí a sì ní ìṣemọ́tótó àti àtúnṣe lọ́kàn
- Agbègbè ilé ìgbọnsẹ̀ súnmọ̀ra kí ó lè jẹ́ ibi tí kò jìnnà sí ilé ìgbọnsẹ̀ fún ọmọdé tí ó ní SCD

***Eŕe Ìdarayá:*** Yẹra fún eré ìdarayá tí ò le fa ìnira ipá nínú tí ó lè fa ìdárúdàpọ̀ àrùn inú ẹ̀jẹ̀. Fàyègba eré ìdarayá níwọ̀nba. Fetísílẹ̀ sí ọmọ nàá tí yóò wa mọ̀ nípa ìwọ̀n nípa ohun tí ó lè ṣe. Fún ẹni tí ó ní SCD máṣe kọ̀ nígbà tí wọ́n bá bèrè fún àyè láti ma kópa tàbí dúro nítorí rírẹ̀ tàbí ìrora. Fún àwọn ọmọ tí ó ní SCD, àwọn ohun tí ó lè ṣòkunfa ìdárúdàpọ̀ tàbí àìsàn ní òtútù tàbí ojú ọjọ́ tútù, tàbí ṣíṣí ara sílẹ̀ sí òtútù. Ó ṣe pàtàkì láti tẹ́tí sílẹ̀ sí ọmọ àti òbí, àti láti tẹ̀lé ìmọ̀ràn àwọn onímọ̀ ìlera wọn.

**Ìhùwàsí tó Dára: Àìsàn Ibà**

Àìsàn ibà yára pa àwọn ọmọdé tí ó ní SCD. Ilé ẹ̀kọ́ kan ti ṣètò kí a fi àwọ̀n apẹ̀fọn sí gbogbo ojú fèrèsé/àbáwọlé. Fún ilé ẹ̀kọ́, lo àwọn ọṣẹ àkànṣe tí ó ní DEET. Gbogbo àwọn ọmọ tí ó ní SCD gbọ́dọ̀ gba ogùn agbògúnti àìsàn ibà lọ́fẹ̀. Gba àwọn òṣìṣẹ́ ilé ẹ̀kọ́, akẹ́ẹ̀kọ̀ àti òbí níyànjú láti ṣe ìtọjú àyiká wọn kí àkókò òjò tó dé láti dín ibi ìbisí ẹ̀fọn láti pọ̀ si láwọn àyiká ilé ẹ̀kọ́. Irufẹ́ àwọn iṣé ìgbógun tí àìsàn ìbà ran ọmọdé tí ó ní SCD lọ́wọ́ àti àwọn ọmọ míìràn tí ìbà lé mú lọ́wọ́, dé ìpele kan, pé kí wọ́n ní àìsàn ìbà tí ó pọ̀

***Àkóràn:*** Àwọn ọmọdé tí ó ní SCD lèní ọlọ inú tí ó ti bàjẹ́ àbi tí kòsí níbẹ̀ (ẹ̀yà inú tí ó ń ṣe ìrànwọ́ ní gbígbogun ti àkóràn) ó sì ń jẹ́ kí àkóràn tètè ràn wọ́n. Ó ń fàyegba ìkópamọ́ àti ìpín kiri irúfẹ́ yóò wù ògùn agbógunti tí a fún àwọn ọmọ tí ó ní ségesège àrùn inú ẹ́jẹ̀.

**Ìhùwàsí tó Dára: ÌWỌ̀N ÒTÚTÙ**

Àwọn ọmọdé tí ó ní SCD lè ṣàìsàn bí wọ̀ń bá gbóná tàbí tutu jù. Bí òtútu báwà jẹ́kí wọ̀ń wọ aṣọ ìlọ́wọ́wọ́ nínu kíláàsì. Akò gbọ̀dọ̀ gbàwọ́n láyè láti jáde ìṣeré bí òjò bá ń rọ̀, tutù tàbí ń fẹ́ atẹ́gùn. Òṣìṣẹ́ tó ń ṣàbojútó àkókò ìṣeré, bí amúgbálẹ́gbẹ̀ tàbí òṣìṣẹ́ oúnje alẹ́, ní a gbọ́dọ̀ ṣàlàyé fún láti má fi ipá mú wọn ṣe èyí. Ọmọ Ẹgbẹ́ Ìgbimọ̀ Ìṣakóso Ti Ilé Ẹ̀kọ́ gbọ́dọ̀ ṣiṣẹ́ pẹ̀lú òbí láti fẹnukò nírúfẹ́ aṣọ ilé ẹ̀kọ́ tàbí ètò láti fàyegba àwọn ọmọ tí ó ní SCD láti wọ aṣọ tí ó tọ́ ní àkókò ọdún. Síwájúsi, ní ojú ọjọ́ tó nira, gbóná tàbí tutù, aṣọ ilé ẹ̀kọ́ àti àkókò ṣíṣí ní a gbọ́dọ̀ ṣàgbéyẹwò ní ìbámu pẹ̀lú sáà. Óṣe pàtàkì kí a yẹra fún ọ̀pọ̀jù ènìyàn nínu ìyàrá ìkẹ́ẹ̀kọ̀ bí ilé ẹ̀kọ́ míìràn ti ní ọmọ tí ó pọ̀jù, àwọn ohun èlò ni a sì ń lò lálòjù. Àpọ̀jù èrò nínu ìyàrá ìkẹ́ẹ̀kọ̀ lémù àgbègbè ìyàrá ìkẹ́ẹ̀kọ̀ dí, gbóná, ósì lè fa àìrí atẹ́gùn mí dáadáa kí ò si fa àìda ara ẹni tí ó ní SCD. Ẹni tí ó ní SCD gbọ́dọ̀ yẹra fún ẹ̀rọ amúlétutù nítorí afẹ́fẹ́ tútù wọn lè fa ìdárúdapọ̀ àrùn ínu ẹ̀jẹ̀.

***Ètò Ìtọjú Ìlera Ẹnìkankan:*** Gbogbo ọmọ tí ó ní SCD ni ó gbọ́dọ̀ ní ètò ìtọjú ìlera ẹnìkankan, èyí tí wọ́n gbọ́dọ̀ ṣe àyẹ̀wò lọ́dọọdún. Níwọ̀n ìgbà tí SCD ni àwọ̀n àkobá orísii tí ó ń kóbá ẹ̀ya ara, ó ṣe pàtàkì, níbi tí ó ti ṣéèṣe, kí a fi akọ̀ṣẹ́-mọṣẹ́ òṣìṣẹ́ onílera ti àrùn inú ẹ̀jẹ̀ láti ṣàgbékalẹ̀ ètò. Àwọn míìràn lè jẹ́ àwọn Ọmọ Ẹgbẹ́ Àrùn Inú Ẹ̀jẹ̀ ti àyiká.

**Ìhùwàsí tó Dára: Ètò Ìtọjú Ìléra Ẹ̀nìkọ̀kan**

Gbogbo àwọn ọmọ tí ó ní àìsàn nílé ẹ̀kọ́ gbọ́dọ̀ ní ètò ìtọjú ìléra ẹnìkankan. Onísẹ́ ìlera ilé ẹ̀kọ́ tí ó ní ìmọ̀ dáradára nípa SCD àti àwọn aàrun búburú míìràn ni a gbọ́dọ̀ gbé kalẹ̀. Ètò ìléra ilé ẹ̀kọ́ ni a gbọ́dọ̀ gbékalẹ̀ láti ọwọ́ Ẹgbẹ́ Ìlera Ilé Ẹ̀kọ́ tí a ṣàlàyé ìjẹ́ ọmọ ẹgbẹ́ rẹ̀ nínu Àkóso Ìlera Ilé Ẹ̀kọ́. Ètò Ìtọjú Ìléra ni a gbọ́dọ̀ ṣàgbékalẹ̀ pẹ̀lú ìbájíròrò pẹ̀lú òbí àti àwọn ọmọdé. Ètò yíi jẹ́ tẹlẹ́nikankan ṣùgbọ́n ó gbọ́dọ̀ ní: gbèndéke ìyẹrafún láti mú ọmọ wà ní ìlera ní ilé ẹ̀kọ́; ìpèsè fífún ọmọ ní ògùn ara ríro; ohun tí ó ń fa pàjáwírì àti kíni alèṣe; àwọn olùkànsí gbòógì, pàápàá jùlọ ajùmòsọrọ̀ (ọ̀jọ̀gbọ́n oníléra pàtàkì tí ó ń tọ́jú ọmọ); àti àkọsílẹ̀ gbogbo òṣìṣẹ́ ilé ẹ̀kọ́ kíi ṣe olùkọ́ nìkan) tí o ti lọ ibi ìdánilẹ́kọ̀ lóri SCD. Bí ó ti yẹ, a máa ń ṣe àtúnyẹ̀wò ètò yíi lọ́dọọdún, a sí ń ṣàyẹ̀wò láti ní ìdánilójú pé gbogbo oṣìṣẹ́ tí ó ṣeṣe fún ọmọ yì láti ṣalábàpádè lákòkò ọdún ìkẹ́ẹ̀kọ̀ ti gba ìdánilẹ́kọ̀.

**Ohun to Jẹmọ Egbogi ati Egbogi Pajawiri fun Segesege Arun Inu Ẹjẹ (SCD)**

***Àmì àyà dídùn:*** Àwọn àmì pẹ̀lú àyà dídùn, ikọ́ híhú, mímí nínú ìrora, àti ibà. O lè farajá àmì ọ̀rìn. Ṣùgbọ́n, ó ṣe pàtàkì láti kànsí olùkànsí kíákíá.

***Ìdúró ẹ̀jẹ̀ fún sáà kan:*** Èyí ni nígbà tí ihò egungun fà sẹ́hìn ní pìpesè ẹ̀jẹ̀ pupa sí iṣan fún ìgbà kan an, èyí maa ń wáyé nítori àkóràn pẹ̀lú kòkòrò tí a mọ̀sí ParvovirusB19. Èyí fa kí ẹ̀jẹ̀ pupa inú iṣan ó wálẹ̀ àti àìní ẹ̀jẹ̀ tó. Lára àmì ni rírù gan an àti rírẹ̀, àti ìmísòkèsódò.

***Ibà:*** Àwọn ọmọ tí ó ní àìṣedédé àrùn inú ẹ̀jẹ̀ maa sábà ní àkóràn àwọn kòkòrò inú ẹ̀jẹ̀ kan. Ìbà bíi 101° Fahrenheit (38° Celsius) tàbí ju bẹ́ẹ̀lọ, lè jẹ́ àmì àkóràn. Àwọn ọmọ tí ó ní àìṣedédé àrùn inú ẹ̀jẹ̀ àti ibà ni kí olùkańsí(paediatric haematologist) rí láìfi àkókò ṣòfò.

***Àmì Ọwọ́-ẹsẹ̀ dídùn*** (tí a mọ̀sí dactylitis): Ìrora wíwú tí ọwọ́ àti ẹ̀sẹ̀, pẹ̀lú ìbà. Ó sábà maa ń ṣẹlẹ̀ láàrin àwọn ọmọ lábẹ́ ọdun márùn un. Ó ṣe pàtàkì kí àwọn oṣìṣẹ́ ilé ẹ̀kọ́ nọ́sìrì àti jẹ́lé-ó-sinmi láti mọ̀ èyí láti yẹra fún ẹ̀sùn èké ìjàm̀bá ìpàlára.

***Ìdàrúdápọ̀ Ìrora:*** Èyi lè wáyé ní ẹ̀yà yóó wù ní ara ó sì lè wáyé nítorí òtútù tàbí oru, àkóràn tàbí gbígbẹ omi ara. Èyi lè ṣẹlẹ̀ fún wákàtí díẹ̀, bí ọ̀ṣẹ̀ méjì, tàbí ju bẹ́ẹ̀lọ, ó sì le pọ̀ tóbẹ̀ẹ tí a lè gbé ọmọ lọ ilé ìwosàn. Ó ṣe pàtàkì láti fetisí ọmọ tí yóò wá mọ̀ bóyá ìnira náà jẹ́ díẹ̀/ìwọnba tí yóò sì kọja (níbi tí ilé ẹ̀kọ́ lè ṣe agbélarugẹ ilé ẹ̀kọ́ nípa fífàye gba ìsinmi àti gbígba padà sí ilé ẹ̀kọ́ bóyá) tàbí bóyá wọ́n nílò láti lọ ilé ìwosàn.

***Ìrora fífẹ̀ ọlọ inú:*** Ọlọ inú yóò fẹ̀ yóo wà mú iṣan ẹ̀jẹ̀ pupa bíi gọ̀gọ̀ sínú. Èyí maa ń jásí ìbà iṣan ní gbogbo ara. Àmì ìbẹ̀ẹ̀rẹ̀ ni rírù, rírẹ̀, àti fífẹ̀ ọlọ inú, àti ìnira inú. Ó ṣe pàtàkì kí àwọn òṣìṣẹ́ ilé ẹ̀kọ́ alákọ̀bẹ́rẹ̀ àti jẹ́lé-ó-sinmi mọ ìṣẹlẹ̀ tí ó ń dún kokò mẹ́mi yìi, bí ó ti ṣe lè wà nínu àwọn ọmọdé.

***Àrùn àìṣiṣẹ́ ọpọlọ:*** Ó máa ń wáyé jùu láàrín àwọn ọmọ ọdún méjì sí méwà. Lo ìlànà FAST:

**Rírẹ̀ Ojú: ṣé ẹni náà le rẹ́rìn, tàbí ojú tàbí imú ṣí sílẹ̀?**
**Apá: ṣé ọmọ náà le gbé apá méjèjì sókè kọjá ìpele ejìká?**
**Ìṣoro ọ̀rọ̀ sísọ: ṣé ẹni náà lè sọ̀rọ̀ kétékete kí ohun tí ó sọ ye?**
**Àkókò: láti gba ìrànwọ́ ìwòsàn pàjáwìrì.**

Ó ṣòro láti ya àmí àrùn àìṣiṣẹ́ déédéé ọpọlọ kúrò ní ti ìdàrúdápọ̀ àrùn ẹ̀jẹ̀, níbi tí ìnira lè fa àìlèrìn déédéé. Àwọn ọmọ tí ó ní SCD nílò àyẹ̀wò wíwo inú àwọn iṣan láti ọdún méjì láti wo ewu àrùn àìṣiṣẹ́ ọpọlọ.

**Àrùn àìṣiṣẹ ọpọlọ tó farasin:** Àyípadà ní ìhùwàsí ọmọdé tàbí ìfọ̀kànsí tàbí àìṣedédé tó ń wáyé nínu ojúlówó iṣẹ́ ilé ẹ̀kọ́ wọn lè wáyé nítorí ọ̀pọ̀ ìdí. Láàrín àwọn ọmọdé tí ó ní ségesège àrùn inú ẹ̀jẹ̀, nítorí àìsàn déédéé ẹ̀jẹ̀, apákan ọpọlọ wọn lè bàjẹ́. Ó ṣe pàtàkì fún olùkọ́ láti jíròrò ìyípadà nínu ìwà tàbí ìṣedédé ìkẹ́ẹ̀kọ̀ pẹ̀lú òbí tí ó le sọpé irúfẹ́ bíbàjẹ́ bẹ́ẹ̀ ń ṣẹlẹ̀. Ó ṣe pàtàkì láti ran òbí lọ́wọ́ láti so wọ́n mọ́ ilé ìwosàn àgbègbè láti ṣe ìwádì bóyá irúfẹ́ ìyípadà ìhùwàsí ń wáyé nítorí àrùn àìṣiṣẹ́ ọpọlọ tó farasin.

***Ìnàró àti ìrora okó:*** Ìrora ìnàró okó tí a kòfẹ́, tí kò jọmọ́ èrò nípa ìbànílopọ̀. A gbọ̀dọ̀ wá ìrànwọ́ ìṣègùn kíá bí èyí bá pẹ́ fún bíi wákàtí méjì.

**Báwo ni ènìyàn ṣe ń ní ṣégeṣège arùn inú ẹ̀jẹ́ (SCD)?**

A máa ń jogún ségesège àrùn inú ẹ̀jẹ̀, tí ó ń ràn láàrín ẹbí. Kìí ṣe àrùn àkóràn kòsì le ran ènìyàn bíi ikọ́ tàbí òtútù. Àwọn tí ó ní àrùn ìnù ẹ̀jẹ̀ ni a sábà maa ń pè ní ẹni tí ó ní ipá àrùn ẹ̀jẹ̀ nínu iṣan. Àwọn tí ó ní gínì tí ó ṣe déédéé tí ó ní àkóràn. Níti àwọn tí ó ní àrùn inú ẹ̀jẹ̀, ẹ̀jẹ̀ wọn ní ẹ̀jẹ̀ pupa tí ó wọ́pọ̀ (ẹ̀jẹ̀ pupa àgbà, ẹ̀jẹ̀ pupa A) àti àrùn inú ẹ̀jẹ̀ pupa (ẹ̀jẹ̀ pupa S). Olùní àrùn yíi sábà maa ń wà ní ìlera fúnra wọn, wọ́n sìle má mọ̀ pé àwọn ní ipa àrùn ìnú ẹ̀jẹ̀ àfi bí wọ́n bá lọ fún àyẹwò ẹ̀jẹ̀. Bí ènìyàn bá ní ipa àrùn inú ẹ̀jẹ́ kòle di ségesège àrùn inú ẹ̀jẹ̀. Fún àpẹẹrẹ, Bí tọkọtaya bájẹ́ alárùn inú ẹ̀jẹ̀ (ẹ̀jẹ̀ pupa AS), nígbà náà **ni oyún Kànkan** ó ṣèeṣe pé ọ̀kan láàrín mẹ́rin nínu ọmọ wọn lè ní àrùn inú ẹ̀jẹ̀ (ẹ̀jẹ̀ pupa SS, irúfẹ́ àrùn inú ẹ̀jẹ̀); ọ̀kan nínu mẹ́rin ọmọ tí ó ní ẹ̀jẹ̀ pupa tó da (ẹ̀jẹ̀ pupa AA), àti ọ̀kan láàrín méjì ọmọ tí ó ń gbé àrùn yíi nínu ẹ̀jẹ̀ kiri (AS).

**Ìhùwàsí tó Dára: Àrùn Ẹ̀jẹ̀ nínu Kọ̀ríkúlọ́mù**

Ọ̀nà kan láti ṣẹ̀dá irúfẹ́ ìlànà ẹ̀kọ́ tó yèkoro ni láti jẹ́ kọ̀ríkúlọ́mú wuyì fún akẹ́ẹ̀kọ̀. Irú ìlànà àjogúnbá gínì ti àrùn inú ẹ̀jẹ̀ ni a ní láti fi sí àrín gbungbun kọ̀ríkúlọ́mù ẹ̀kọ́ ìmọ̀ sáyẹ́nsì. Àwọn Ẹgbẹ Alárùn inú Ẹ̀jẹ̀ tí UK ti ṣe ìlànà ìtọ́ni bí a ṣèle fí àrùn inú ẹ̀jẹ̀ sínú kọ̀ríkúlọ́mù gbogbo ìpele ẹ̀kọ́ **http://www.sicklecellsociety.org**

***Ìrora:*** SCD jẹ́ ipò tí a kòle sọ pàtó rẹ̀, ó ń yí ní gbogbo ìgbà àti láàrín oríṣii ènìyàn. Ẹ̀yí ṣòkunfà àìmọ̀ èyí tàbí tọ̀hún fún ọmọdé. Ìrora ìdarúdápọ̀ yíi lè wá lójijì. Ìrora lè jẹ́ kí ènìyàn maa kanra, má dásí ǹnkan tàbi fọwọ́sowọ́pọ̀. Ìrora ìdarúdápọ̀ àrùn inú ẹ̀jẹ̀ lé má pọ̀, pọ̀ díẹ̀ tàbí pọ̀ gan an. Níwọ̀n ìgbà tí ìrora jẹ́ ìrírí tó wọ́pọ̀ fún àwọn tí ó ní SCD ó ṣe pàtàkí kí ilé ẹ̀kọ́ ṣàgbékalẹ̀ ìlànà láti ṣe ìrànwọ́ fún àwọn ọmọ nínu ìrora. Ìlànà ìtọjú yìi gbọ́dọ̀ jé fún ọmọ Kankan, pẹ̀lú ìdásí lọ́dọ̀ olùkọ́, nọ́sì ilé ẹ̀kọ́, akọ́ṣẹ́mọṣẹ́ nọ́sì alárùn inú ẹ̀jẹ̀. Ó ṣe pàtàkì kí ìlànà náà ní ìtọ́ni nípa fífúnni ní aporó (èyí tí ó ní ẹni tí ó mọ bí a ṣe ń fúnni lóògùn, irufẹ́ aporó wo àti ìpinnu èwo laa fúnni).

***Òògùn***: Kókó lára Ètò Ìtọ́jú Ìlera Ẹlẹ́ni-kọ̀ọkan ni ìpèsè fún fífúnni lóògùn, àti ọ̀nà láti mọ bí ìrora ṣe pọ̀si. Kókó rẹ̀ ni kí a tẹ́tísí ọmọdé. Níbi tí ìrora ò ti pọ̀ tàbí bí ó bá jẹ́ díẹ̀ kókó rẹ̀ ni kí a fí ọmọ sí ilé ẹ̀kọ́, nípa pípa òògùn ìrora mọ́ ànfàànì fún ìsinmi àti ìjáde ní àgbègbè tí ó pamọ́ kí wọ́n lè padà sí ẹ̀kọ́ nígba tí ó báyá lóòjọ́. Ìlànà tó farajọ ohun lórí àìfúnni lóògùn tàbí àbájáde níní ọmọdé ní lílo òògùnkógùn yóò jẹ́ ìlànà tí kò dára fún ọmọdé tí ó ní ségesège àrùn inú ẹ̀jẹ̀.

***Mímọ̀ Olùkọ́:*** Gbogbo òṣìṣẹ́ gbọ́dọ̀ mọ̀ nípa àrùn inú ẹ̀jẹ̀. Àwọn ilé ẹ̀kọ́ kan maa ń ṣe èyí nípa fífisí ìdánílẹ́kọ̀ lórèkoorè fún àwọn olùkọ́. Òṣìṣé gbọ́dọ̀ mọ ohun láti ṣe bí ọmọ bání ìdàrúdápọ̀, bí a ṣe ń mọ àmì àti àpẹẹrẹ àrùn ọpọlọ lára ọmọdé tí ó ní SCD, kíkọ́ láti tẹtisí ọmọ bí ọmọ bání òun ní ìrirí àìdá ara. Ridájú pé kó tó dára wá fún ṣísàlàyé ìwifún nígbà tí ọmọ báni olúkọ toto, nígbà tí wọ̀n bá yí kílàasì padà tàbí nígbà tí wọ́n bálọ ilé ẹ̀kọ́ míìràn. Ridájú pé ìpesè wà fún ibi àbò fún akẹ́ẹ̀kọ̀ tí ó ní SCD láti wà lálàáfíà kí ó sì yẹra fún akitiyan. Wọ́n lè padà sí ìkẹ́ẹ̀kọ̀ bóyá ní ọjọ́.

***Ìdójúkọ Ìyàsọ́tọ̀:*** Ridájú pé a ṣàjọrò SCD gẹ́gẹ́bí ara t'Ẹlẹ́ni, Ìlera àti Ìbálopọ̀ Ẹ̀kọ́ kí ó sì ridájú pé àwọn akẹ́ẹ̀kọ̀ míìràn ri ìdójúkọ lóri ìwò ìyàsọ́tọ̀.

**Àgbékalẹ̀ iṣẹ́ fún Ètò Ìtọ́jú Ìlera Ẹlẹ́ni-kọ̀kan fún Àwọn tí ó ní Ségesège Àrùn Inú Ẹ̀jẹ̀ kan**

| | |
|---|---|
| Orúkọ:<br><br>Ọjọ́ Ìbí:<br><br>Ilé Ẹ̀kọ́:<br><br>Kíláásì tó wà/Ẹgbẹ́:<br><br>Ipò 1: Àrùn Inú Ẹ̀jẹ̀ (HbSS)<br><br>Ipò 2:<br><br>Ipò 3:<br><br>Ọjọ̀ Àgbékalẹ̀:<br><br>Àgbéyẹwò Ọdún kọ̀ọ̀kan: | <br>Aworan |
| **ÀKÀNSÍ ÒBÍ/ALÁBÒJÚTÓ/ OLÙTỌJÚ ỌFẸ́**<br>**Orúkọ Olùbásọ̀rọ̀:**<br>**Ìbáṣepọ̀:**<br>**Nọ́ḿbà Olùbásọ̀rọ̀:**<br><br>**Orúkọ Olùbásọ̀rọ̀:**<br>**Ìbáṣepọ̀:**<br>**Nọ́ḿbà Olùbásọ̀rọ̀:** | **NỌ́ḾBÀ OLÙBÁSỌ̀RỌ̀**<br><br>**Orúkọ Pàjàwírì Olùbásọ̀rọ̀:**<br>**Nọ́ḿbà Pàjàwírì Olùbásọ̀rọ̀:**<br><br><br>**Orúkọ Ilé ìwosàn (Haematologist):**<br>**Nọ́ḿbà Ilé ìwosàn (Haematologist):**<br><br>**Orúkọ Nọ́sì Akọ́ṣẹ́mọṣẹ́:**<br>**Nọ́ḿbà Nọ́sì Akọ́ṣẹ́mọṣẹ́:** |
| **AWỌṅ OṢIṢẸ PATAKI NILE ẸKỌ:**<br>Orúkọ:<br>Ilé/Ẹ̀ka:<br>Nọ́ḿbà Olùbásọ̀rọ̀: | **DỌKITA ẸBI**<br>**Orúkọ Olùbásọ̀rọ̀** |
| **Ọjọ́ tí a ṣe Àyẹwò Àbò Ewu tí a ṣe n'Ílé Ẹ̀kọ́:** | |
| **IDADURO:**<br><br>**Àwọn òṣìṣẹ́ Pàtàkì ní láti ripé ẹni kọ̀ọ̀kan nínu àwọn òṣìṣẹ́ ilé ẹ̀kọ́ mọ ìwúlò àwọn ìdádúró wọ̀nyíi….**<br><br>*Aye ainidilowo si omi mimu lakoko ikeeko*<br>*Aye ainidilowo si ile igbonse, pelu akoko ikeeko*<br>*Isora ni gbogbo ona si iba*<br>*Aifi ipa muwon ni akoko ere idaraya bi won bani o re won tabi ni irora* | |

**ÒÒGÙN**

**Orúkọ òògùn:**

**Èrèdí fún òògùn:**

**Ìwọn òògùn:**

**Àkókò òògùn lílò:**

**Ìfiyèsí Ọ̀tọ̀:**

**Ìtọ́jú òògùn:**

**Ètò Ìkólọ sí Ilé Ẹ̀kọ́:**

**Ètò Àkọsílẹ̀:**

**ÌSÀKÓSO ÌRORA**

Èrò ni láti mú ìwọntúnwọ̀nsí bá ìfèsì sí ìloogùn pàjàwírì bí o ṣe yẹ àti ṣíṣàkóso àgbègbè ilé ẹ̀kọ́ tí ó yẹ níbití akẹ́ẹ̀kọ́ tí ó ní àrùn ségesège inú ẹ̀jẹ̀ kíi tí di ẹni alelọ̀ ilé lóòrekoorè nítorí ìrora díẹ̀. Bèèrè lọ́wọ nọ́sì onímọ̀ nípa àrùn inú ẹ̀jẹ̀ tàbí ile olùkànsí ìwòsàn bì ìwọn ìrora fún lílo báwá tí a le lò láti le jẹ́ kí ọmọdé tí ó ní àrùn inú ẹ̀jẹ̀ sọ bí ìrora ti wọ́n wa ṣè tò. Ìwọn wa tí a o ṣe àfihàn àwòrán yíya àwòrán apanilẹ́rìn oríṣiríṣi ojú fún ọmọde láti ìdùnnú (láìsí ìrora) sí ìbànújẹ́ àti ẹkún (ìrora ní gbogbo ìgbà). Irufẹ́ ìwọn yíi lè pẹ̀lú ètò ìtọjú ìlera ẹlẹ́nikọ̀ọ̀kan. Àwọn ìwọn yii wa fún alaye ṣiṣe nìkan àti pé ìwọn yóowù tí a lò gbọ́dọ̀ ní ìgbàyè olùkànsí ọmọdé láti ilé ìwòsàn (haematologist).

| 0 | 2 | 4 | 6 | 8 | 10 |
|---|---|---|---|---|---|
| | | | ✓ | | |
| Nkò ní ìrora | Moní ìrora díẹ̀ ṣùgbọ́n mí ò nílò òògùn | Mo lérò pé bí mo bá lo òògùn mi mo lè wà ní kíláásì | Mo lérò pé bí mo bá sinmi ara mi á dá bóyá | Mo rò pé ó yẹ kí n lọ ilé | Mo rò pé ó yẹ kí n lọ ilé ìwòsàn |

**ÀWỌN OHUN ÌWÚLÒ MÍÍRÀN/ǸǸKAN**

*Ipele yii le ni iwifun oto fun ipo omode kookan (fun apeere, iwifun nipa arun opolo ti o dake, egbo ese adaijina, airo oko omokunrin, efori, imulojiji tabi awon isoro ti segesege arun inu eje).*

**Awọn oniikan ti nṣe IHCP**

Orúkọ Ènìyàn: Ìbuwọ́lù: Déètì:

Alabojuto/Olutọju ọfẹ: Ìbuwọ́lù: Déètì:

Nọsi Ile Ẹkọ: Ìbuwọ́lù: Déètì:

Nọsi Akọṣẹmọṣẹ onimọ Arun inu Ẹjẹ: Ìbuwọ́lù: Déètì:

Olùkọ́: Ìbuwọ́lù: Déètì:

**Oṣiṣẹ ile ẹkọ Ti O Ti Gba Idanilẹkọ Lori Arun Inu Ẹjẹ:**

| Orúkọ: | Déètì: |
|---|---|
| | |
| | |
| | |
| | |
| | |
| | |

**Àlàfo gbọ̀dọ́ ní àpẹẹrẹ tí ìṣesí tí ó dára tí ilé ẹ̀kọ́ ṣàgbékalẹ̀:**

**Omi**

*[Oruko] ni aaye lati gbe ike omi re lo apejo. O joko lehin ila ki o le laaye si eyi.*

**Iṣẹ́**

*Lo eya ere idaraya miiran lati se igbelaruge ifisi a.p. itoju-maaki, ilo aago ere idaraya*

**Fún Ìfà Ẹ̀jẹ̀ fún Ségesège Àrùn Inú Ẹ̀jẹ̀**

*Sise pelu ile iwosan lati seto ifun leje loreekoore kii [oruko] le ni okun nibeere akoko idanwo.*

**Ìwifún Sii**

**<u>ÌWÁDÌÍ</u>**
Fún ìsopọ̀ sí ẹ̀rí ìwádìi tó ṣàfihàn iṣẹ́ ìwifún yìi, jọ̀wọ́ lọsí:
http://www.sicklecelleducation.com

Ojula yii ni awọn ipinlẹṣẹ eroja ti a ṣagbekalẹ fun awọṅ olukọ ni UK, ninu rẹ ni:

*Ọmọ ikẹẹkọ mi ni Arun Inu Ẹjẹ [Iwe pelebe]*
*Ọrẹ mi ni Arun Inu Ẹjẹ [Iwe pelebe]*
*Wh*Ohun lati Ṣe bi o ba Fura pe Akẹẹkọ ni idarudapọ Arun Inu Ẹjẹ [Iwe Alẹmọle]
Arun Inu Ẹjẹ ati Arun Ọpọlọ *[Iwe pelebe]*

**<u>ẸGBẸ ATINU-DAPỌ ARUN INU ẸJẸ</u>**

**SCORE Ẹgbẹ́ Ìwádìi Àrùn Inú Ẹ̀jẹ̀**
http://www.score-international.org/

**Àwùjọ Àrùn Inú Ẹ̀jẹ̀ Ti UK**
http://www.sicklecellsociety.org

**Awọn Onla ninu ewu kekere ti Arun Ọpọlọ ati Arun Inu Ẹjẹ (Cardan, Nigeria)**
http://www.scyss.org

**Èròjà Arun Inu Ẹjẹ, Nigeria**
**http://www.sicklecellfoundation.com/**

**<u>EROJA MIIRAN</u>**

**Iṣẹ Ilera Apapọ UK ati Eto Iṣayẹwo Ẹjẹ**
http://www.sct.screening.nhs.uk
Fun ẹda agbawalẹ si *Idari Obi si Itọju ati Iṣakoso Ọmọ rẹ ti o ni Arun Inu Ẹjẹ*

**Ohun Elo Ẹkọ Gbangba fun Arun Ẹjẹ ati Arun jẹjẹrẹ ti o ṣakoba iṣe ati irisi ẹjẹ**

http://www.sicklecellanaemia.org/
Fun aworan arun ẹjẹ ọfẹ ati awọn ohun elo ẹkọ gbangba

Ìgbàwálẹ̀ ẹda iwe pelebe yii wa ni:

www.sicklecelleducation.com
www.sicklecellanaemia.org
www.score-international.org

Aṣeda iwe pelebe yii ni 2011 lori iwasi ti United Kingdom Economic and Social Research Council (RES-000-23-1486) ṣe ikinlẹhin, iwadii ti Simon Dyson, Lorraine Culley and Sue Dyson (De Montfort University); Karl Atkin (University of York) ati Jack Demaine (Loughborough University) ṣe.

E·S·R·C ECONOMIC & SOCIAL RESEARCH COUNCIL

Ẹya Gbogboogbo Naijiria Deeti: 25th Oṣu Ọwawa 2012